The Chief Secretary to the Govt


# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. No. [illegible]02 SATURDAY, NOVEMBER 24, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



...5 DEC 1928 ...AGOS



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[*A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.*]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

## EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[*Fun Atọsi lailai ati titun.*]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.


SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
LOOK FOR THE PORTRAIT OF
D. Earl S. Sloan
TO STOP YOUR ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale: Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd. London Eng.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

EYI NKỌ?

Ihin kan ni lati Sapẹli pe Adajọ ibẹ bu poun meje ( £7 ) ni sisan sinu apo Ọba fun ẹṣẹ pe Lọya kan ba Ọlọpa kan nibẹ ja lẹnu iṣẹ rẹ, a sọ pe lati ilẹ yi ni Lọya na ti lọ si Sapẹli.

Eyi ma ki o.

DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

OLORE LỌ!

Ni ọjọ Alamisi ijẹta ti nṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi lo di ọdun marun ti a gbọ iku Alaji Falm, ti gbogbo aiye mọ ni oninu rere ati ẹni Ọlọrun : Nwọn ṣe isinku rẹ ni ọjọ kẹtalelogun oṣu, ni ọjọ Jimọ, ọjọ keji rẹ larin ogunlọgọ awọn ara ilu ati larin ẹyẹ—ọrun yẹ ẹ o, Alaji olore, ki Ọlọrun Olodumare ki o dẹlẹ fun u, ki o si fi inu rere rẹ han : A sọrọ Iranti diẹ nipa iku ati igbesi rẹ si inu wesika wa ti oni.

ỌRỌ ẸRIN.

Ẹrin o wo ni horo kan ti nwọn npe ni Tairu Lane, ni owurọ ọjọ *Monday* ijẹta nigbati Tolotolo ati akukọ adiẹ kan wọ iya-ija, bi enia ti duro ka nwo ran wọn ni eyi—nwọn ja titi o fẹrẹ gba wọn to iwọn ogun iṣẹju nitoripe nigbati a tun rekọja bọ a ba wọn ni ẹnu ija na, ija wọn dabi igbati enia iba ma wo ran sinima.

KI Ẹ SUN 'RAKI.

Ti ọdun ba mbọ bayi li a ma ngburo awọn "arabi" awọn afamọlori-iyagbẹ ko si ẹniti ko ye nmu wa nitorina ki olukuluku mura lati ma boju to inu ile rẹ, ki nwọn ma ba parada fun ẹlomiran.

GIRI LO KAN NI.

A gbọ wipe bi motor alupupu kan ti mbọ ti motọ papa kan si mbọ lojiji ni nwọn ṣe pẹkiriki ra wọn ni Broad Street, ni ọjọ Atalata to kọja, bẹni awọn oyinbo ti o mbẹ ninu mọto lọtun-losi yọ foro ni nwọn si ṣe ajo arawọn, ni olukuluku fi ba tirẹ lọ, ohun kekere lo nṣẹṣẹ.

INA ỌBA.

O jẹ ohun iyalẹnu fun wa lati ma ṣe akiyesi ina ọba ti awọn ara adugbo Victoria de Oluwọle fa wọ ile, bi o ti nku lẹmẹwa to bẹ ti nwọn ki iri anfani rẹ jẹ nigbamiran ti o yẹ, iba dara bi awọn P. W. D. ba le ṣe akiyesi ohun to ma njẹ ki ina na nku nigbagbogbo bẹ, ohun ti enia nsan owo fun, o ni lati magbadun rẹ bi o ti fẹ.

IWA AGABA-GEBE AWỌN ỌMỌ ANABI ADAMỌ.

( APA KEJI. )

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Awọn tani ẹniti o nya erekere, awon tani ẹniti ko gbagbọ, awọn tani ẹniti o nṣe panṣaga, awọn tani ẹniti o nṣe grimọkayi, awọn tani ẹnti o nṣe agbere, awọn tani ẹniti o nṣoju kokoro, awọn tani ẹniti o njale, ani awọn tani ẹniti o nhu gbogbo iwa buruku ti Oluwa ko fẹ julọ? bikoṣe awọn ẹniti a ro wipe awọn lo nsin Ọlọrun.

Gbogbo awọn iwa wọnyi kọ ni awọn Imale tabi Kiriyo omiran fi nṣe ayọ?

Ninu awọn iwa buruku gbogbo ti a nka yi, a ki nsaba ba awọn abọrişa nibẹ tobẹ, ṣugbọn gẹgẹbi o ti jẹ wipe nwọn ni oluwa miran ti nwon nsin li o fi jẹ wọn niya ni ọjọ idajo, gẹgẹbi Oluwa ti sọ wipe iwọ ko gbodọ ya erekere kan fun ararẹ, bi iru awọn ẹniti o ngbẹ igi ibeji tabi ọmọlangi, tabi awọn ẹniti yio gbe kini kan silẹ ti wọn yio ma ta epo si lori, ti nwọn yio si pa obi abata si idi rẹ, ti nwọn yio ma pe e ni Ọlọrun tiwọn.

Bi ko ba si iru iṣina bayi fun ẹlomiran, ti o si mọ ofin Ọlọrun daradara, dajudaju Oluwa ko ni jẹ oluwarẹ ni iya arara.

Ṣugbọn gbogbo igbagbọ ẹlomiran si Ọlọrun asan on asan ni, nitoripe ọkan rẹ ko mọ to si Ọlọrun, nipa irufẹ iwa buruku gbogbo ti a ni Ọlọrun ko fẹ li a nsọrọ le lori.

Onigbagbọ tabi ẹniti a ro wipe o ni ẹsin dara-dara omiran yio ṣiwaju wọ ina ṣiwaju awọn aborişa, gẹgẹbi a ti ri i ka ninu awọn ọrọ Ọlọrun ti o wi bayi pe, on yio fi ina jẹ awọn alaigbagbọ ni iya lọjọ idajọ.

O jẹ ohun ere ni eti mi lati ma gbọ wipe awọn aborişa kan ni awọn ẹniti gba Ọlọrun gbọ, ti ki yio si de ijọba ọrun, irọ funfun ṣatapata ni eyi jẹ. Ti o ba şe wipe gẹgẹbi Anabi Yisa ati Anabi Mọmọdu ti fi kọ awọn ọmọ Anabi Adamọ ni gbogbo wa tẹle loni ti ẹlomiran ko si di keferi palipali, nipa eyi li a ni ẹnu lati fi sọrọ tabi lati ma fi fa awọn orişa wọn'y nigbagbogbo—eyi ha ri bẹ fun wa lode ti a wa yi loni? (agbẹdọ) a ha ni ẹnu lati ma fi yangunda pe ẹni Ọlọrun pataki kan li a nşe dajudaju a ni ẹnu ṣugbọn ẹnu wa na ko ni lari lati fi yangunda tobẹ iwa ti pakasọ, ti o nkọ adiẹ lẹsẹ, o kun ajadi apẹrẹ.

Emi ti mo nsọrọ yi le pe ara mi ni Kiriyo, mo le pe ara mi ni Musulumi, mo le pe ara mi ni Onigbagbọ ododo, mo le pe ara mi ni ohunkohun ti mo ba fẹ, ki işe wipe ni igbati mo ti pe ara mi ni Musulumi tabi ọmọ ẹhin Yisa nitorina mo ti di ẹniti ara rẹ mọ julọ ati pẹlu tulasi mo ni lati de Alijọnna tabi ọrun rere, ọrun ko jẹ bẹ, mo nfan ara mi jẹni.

Iwa rere ti mba nhu lo le mu mi yangunda pe ọrun rere ni emi yio lọ ati pẹlu Ọlọrun ko ni jẹ mi ni iya arara, ti mba nhuwa rere ti Ọlọrun fẹ ti awọn ọjişẹ rẹ si fi kọ ni ni mo le fi de ijọba ọrun şugbọn laisi eyi yi pabo ni, nitoripe nko pa ofin Rẹ mọ.

Nisisiyi oyinbo paşẹ kan silẹ nwọn si sọ wipe ẹniti o ba tẹ aşẹ na leti awọn yio je oluwarẹ ni iya, dajudaju nwọn ko je je enia ni iya sidi rẹ bikoşe ẹniti o ba tẹ aşẹ na molẹ, gẹgẹ bẹ ni ofin ti Ọlọrun ri, a fi ti oyinbo şe apẹrẹ ti ọrun ki o ba le ye wa daradara, a si mo wipe ohun ti ọpọlọpọ wa ti mọ bayi ni; iwa ẹlomiran loju wa o dabi ẹnipe nwọn nro wipe ko si idajọ.

(*Koi li pari.*)

ỌMỌ-ILU.

---

## ẸNI TO BA FI OJU D'ỌBA—AWOWO AWO.

Ninu ọsẹ yi mo ri ka ninu iwe irohin Daily Times wipe ọmọ jaguda kan to ti lọ si ẹwọn bi ẹmarun ri Adajọ Kotu ọlọpa ni ko lo si ẹwọn ọdun kan nitori pe oji şile kan pẹlu sisi. Eyi fi han nipa iwa buburu ti awọn ọmọ şitani yi nhu ni ilu nipa fifi agbara ja owo gba lowọ mẹkunnu, omiran a mọmọ kọlu ọmọ to nta ọja kakiri wipe ọja rẹ to ba danu, awọn ọmo jaguda yoku, won ayu bo, odi pe ki wọn ji ni nkan, omiran ẹwẹ alọ faya Bicycle ama fi re ọja leri awọn to nkiri, awọn miran awọn yẹn jẹ ọmọ baba mo gbele, wọn a le ara wọn lọ kọlu ẹniti o nlọ jẹjẹ ara rẹ, nipa bẹ a sọ wipe Baba mo gbele lodọ rẹ, iwọ alai mọ kan, wa şọ wipe to tọ ni, nipa bẹ nişe ni ọmọ na ma kọwọ bo ẹ ni apo to si ma yọ owo rẹ lọ, wa wa kan agbako osan gangan, eyi wa nko, ẹnikẹni ti ko ba mọ awọn ti wọn npe ni ọmọ jaguda, to ba di aşalẹ, ko gba oju irin lati ita Faji lọ si Ita Agarawu nibi ti awọn mẹkunnu ẹru Ọlọrun fẹ sọ oja tọro ti di tọrọ pẹlu epini lati ri nkan fi sọta, wa ri awọn elẹgiri wọn yi, nibiti wọn gbe nlọ ti wọn nbọ, ti wọn si nşe awọn ẹniti wọn wa ra ọja lati ilu oke, bi wọn jafara pẹrẹn, ẹgẹle gbe wọn, awon alaparo wọn yi, wọn a şọ Baba onibaba di alalẹ ni şẹju kan, ẹyin ẹnia wa, ẹ o wa ri wipe bi ọwọ ba tẹ ọkan ninu won, o yẹ ki Ijọba da sẹria fun wọn lidai boju wo ehin, ọpọlọpọ enia lo ma şe kayefi nipa ẹjọ ti Lasisi Arẹhin-gbakumo wipe bawo ni awọn Jury şe fi silẹ şngbọn en ti mo fẹ sọ ni wipe bi enia lọ si ẹwọn nigba ta'atin bi wọn ba tun mu, bi ko ba jẹbi ale momo wipe o jẹbi nitori pe awọn Agbagba mejila ti wọn wa idi ẹjọ yi ki won to wa ẹjọ na, wọn ni lati bura ni orukọ Ọlọrun ki wọn to joko nipa ibẹru Ọlọrun wọn ni lati şe otitọ bi bẹkọ Ọlọrun papa yio gbẹsan nipa bẹ ọran awọn ọmọ Jaguda wọn yi, won to bẹru nipa iwa ai mọ Ọlọrun wọn nitori na mo kan sara fun Adajọ nipa ẹjọ oni şile kan abọ yi eyi ajẹ kilọkilọ fun awọn yoku.

## "OTITỌ APẸ OŞIKA APẸ, ILẸ NI YO MỌ ẸNITI O TẸ ON PẸ."

Ọrọ oke yi lo wa si enu wa nigbati a gbọ ki ẹjọ ti Yesufu Iginla pe Wahabi Bajẹla ti Adajọ Agba si fun Yesufu Iginla ni are pẹlu poun meje şile meje owo irin ẹsẹ, asi ki Loya Latunde Johnson L.LB., oku işẹ. Asi tun ki Yesufu Iginla oku aja şẹgun şugbọn mo tẹ fi gbolohun kan han Yesufu Iginla ninu iwe Psalmu ori 119 ẹsẹ 71 to wipe "O dara fun mi ti a pọn mi loju; ki emi ki o le kọ ilana rẹ." Awa rọpe irufẹ ẹjọ yi yio kọ Yesufu Iginla wipe ọran owo kuro ni egbo ile ti afi nda onjẹ koja, iba ija to ja ninu ẹjọ yi yio jẹ kilọkilọ. Mo tun kiọ oku aja şẹgun.

## IKU ORO RẸ DA? ISA OKU AJINDE RẸ DA.

Mo ki awọn Daniel, Emanuel, ati Joseph Bright ati Mrs. Charlotte Mousah ti wọn jade oku arakunrin won ni şọşi U. N. A. ni ọsẹ yi, ẹniti odi Ologbe Ezekiel Ẹbun Akiwande ọkan ninu awọn akọrin ijọ yi nigba aiye rẹ, asi tun ki oniwasu ọjọ na Joseph Bright ẹgbọn Ologbe yi, asi tun ki gbogbo awọn ẹbi Brights papa won ku afẹku arakunrin wọn, Ọlọrun ko pa aşişe rẹ rẹ. Ọlọrun Ọbangiji Ọba Ogo, ko tu iya rẹ ninu, Amin Ẹbun sun re.

### "LỌYA AYO WILLIAMS MO GBA DUN RẸ"

Mo ki Lọya gidigidi nipa awọn ọrọ to sọ nipa awọn awa Motor, ọrọ işiri pupọ ati ọrọ lakaye pupọ lowa ninu rẹ, mo si ro wipe awọn awa Motor, wọn ari si wọn asi fi kọ ọgbọn, nipa irufẹ ti Lọya Williams yi hu eyi fi han bo ti fẹran ilu rẹ si, osi fi ayan to ni han to ti o jẹ wipe ki şe nipa ọna işẹ rẹ, eyi dara pupo ju, gbogbo ara ilu ni wọn gbọ ohun rẹ ti wọn si gbọ ede to sọ, eyi yo fi wọn lọkan balẹ wipe bo ba di ọjọ miran bi asiko Igbimọ ki Igbimọ ba de, ko ni si wipe a gbọ ohun rẹ ri ajeji ohun lo jẹ si wa, ko si ni si wipe a nra ọja okunkun, nipa eyi ọmọ Obi mo gbadun rẹ Ọlọrun a ran ẹ lọwọ.

### ALAYE ! NI YIO MA YIN Ọ VICTOR !

Bi aba bere ohun to mu mi sọro oke iwe yi ma ri sọ, nitori pe awọn kan npa lowe wipe bi ẹgbẹ wọn ba nku, ami ẹrun ama sọ wọn, şugbon awa npa lowe wipe bi ẹgbẹ ẹni ba nşe nkan iwuri inu awa ama dun si, awa asi ma gba rupẹ ti nidi. Bi gbogbo enia ko ri nkan ti Lọya Victor Adedapọ Kayọde şe ninu Assizes awọn ẹbi Eman Savage loko lodo, wọn ha le gbagbe bi? Nipa eyi inu gbogbo ilu ni lati dun bi won ba nri irufẹ Lọya Kayọde to nşişẹ ribi ribi bayi, ki wọn mọ wipe ikan ninu awọn ọmọ wa ti ani lati mu mọra nipa ọran ilu yi ni yi, nitori pe awọn ogbologbo won ni wọn o pa ipo da ni ọjọ kan ti wọn ba darugbo to si jẹ wipe awọn ọmọ wa wonyi ni wọn ma wa nibẹ, nipa eyi adura wa nipe ki Ọlọrun ko ma fun Kayọde ni imọ ọgbọn ati oye pupọ si bi ko si tirẹ ni, işẹ Savage yio bọ yio di ẹniti ami ma wa lorukọ rẹ şugbọn adupẹ lọwọ Ọlọrun ti eyi ko si nibẹ fun Eman Savage ati ẹniti orukọ tirẹ bamu. Şugbọn Victor ewolewo, Dẹmọ tabi People Union or Young Nigerians tabi oşi fara şoko lati fa owo sile ni? Dajudaju ẹniti oba ri ẹ ni ita yio gba fun Ọlọrun, wipe ọkan balẹ. Işẹ rẹ ko ni duro osi ni ri ikọsẹ.

### "WILLIAM ADEDOYIN II, AGO Ẹ O"

Ọmọ onilẹ ntẹ jẹjẹ, ajeji ntẹ giri-giri, ewo lo wa kan Akarigbo pẹlu ọran Eko, nipa wipe okọ letter si Ọba of Lagos wipe Ọlọrun aba şẹgun ọta rẹ, awọn wo lo mọ ni ọta rẹ, tabi ewo lo pe ni ọta on fun ọ, nigbati ode Eko ti Daily Times ni o lọ ki Ọba of Lagos nipa fifi opa rẹ ranşẹ si, mo şe bi akọwe rẹ kọ sinu Daily News wipe ko ri bẹ, tani wa ran ẹ ni eyi to nşe yi ko to wa ni Ọlọrun aba şẹgun ọta rẹ, ọta wo lo mọ wipe oni, ọran to ba kan ni, ni enia nran ẹjọ Jimbo Apena to nro ni ko kọju si, ma da si ọran Eko. Mi o fẹ soju eyi lọ, abọ ọrọ to fun ọmọluwabi, nitori pe Ọba ki şubẹ. Ade amọ ẹ lori O.

### "BẸ BẸ NI KA MA RI O"

Aba ọgbẹni Emanuel Oluyẹle yọ fun ipo Assistant Chief Clerk ti awọn oyinbo rẹ fun, inu wa si dun si, wa tun ri eyi to ju yi lọ ni ẹmi, bo ti nşe ni ko ma şe o.

Anu şe wa pupọ lati gbọ ifarapa ti Ọgbẹni Daniel Bright to nşişẹ ni Printing Office Ebutemetta. Ọlọrun a şe iwosan ko ni nipa o.

### "KO JẸBẸ."

Awọn Şabu Au-Bon Marche ti aya oyinbo Kessler ti kuro ni abẹ ile Sule alapoti nwọn wa bọ si ile Lọya Chris Williams (ologbe) ni ibẹ lẹ o gbe ri ọja ọdun ni orişirişi eyiti obinrin yi şi—ko jẹ ni şabu titun yi ara ni.

---

Gẹgẹ bi a ti ri Ọgbẹni Albert Bright to ti Jos de silẹ yi laipẹ yi ni ilu o fi han wa wipe ilu to njẹ Jos. dara pupọ ko si moru gẹgẹbi Eko yi.

---

Ẹnyin agbagba ati aşiwaju nipo işẹ ti ẹ wa, ẹ jọwọ ẹ ye iwa ifẹra ẹni nikan hu, ẹ fẹran awọn ọmọ lẹhin nyin, ẹ si fẹran awọn ọmọ alakeji nyin, yala iranşẹ tabi alaru gẹgẹ bi ara nyin, kẹ si bẹru Oluwa nipa iwa ọwọ nyin, nitori pe nkan wọnyi ni ẹnyin nşe, awa sa dakẹ. bi ẹ ba bere awa na yio ma ka wọn ni ẹsẹsẹ fun nyin, awa fi eyi fa nyin ni eti na, nitori ko si ẹniti ko mọ ibi ti obinrin ngba bimọ ka to ni kokọ ẹyin si wa, mo sọ eyi fun itju nyin. eyi ani apakan nipa imọran mi fun nyin, nitori pe bi e ko ba yi iwa nyin pada, awa yio ma ka fun nyin ni ọjọ miran.

---

Ni oni ni Igbimo nla asofin yio pade, ohunkohun to ba şẹlẹ nibẹ, a fi eti nyin ba.

---

Ẹ ma gbagbe ni oşu to mbọ yi ni ere ẹşin gẹgẹ bi nwọn ti ma nşe ni ọdun.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ENIA KO DA BI ALLAH.

---

### ORI IV.

### IŞẸ.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KEJILELOGUN.

Ọkan ninu awọn oşelu wa ti lọlọ yi ti o jẹ ijimi ati onişẹ—ẹniti o fi iwe şe igbadun ti o si fi şeşe-şe—ni ologbe Sir George Cornewall Lewis. Onişẹ pa ni işẹ—o kọju mọ işẹ, a-tamatase ati enia ti o baralẹ ni. Ni şise-ntele ni o şe awọn işẹ *President of the Poor Law Board*—on ni o si we ewe işẹ yi—Chancellor, of the

Exchequer, Home Secretary, ati Secretary for War; ọga si ni ninu gbogbo iṣẹ wọnyi.

Nigbati ọwọ rẹ ba dilẹ a ma kọ ẹkọ orişirişi—ti itan, ti ilu ti ijinlẹ ede, ti ẹda enia ati ti awọn nkan atijọ. Awọn iwe ti o ṣe The Astronomy of the Ancients' ati 'Essays on the Gormation of the Romantic Languages' ko ṣe eyi ti awọn ọlọgbọn ọmọwe *Germany* le ṣe.

O kundun awọn ẹkọ ijinlẹ iwọnyi ni o si fi ngbadun ti o fi ndaraya. Lord Palmerston a ma ba a wi pe "o nṣe aşegan" nipa pe a pa iṣẹ rẹ ti nigbati o ba şiwọ ki o ba le ma ka iwe gidi. Palmerstyn papa sọ pe on, ko ri aye a nka iwe gidi—o ni awọn iwe ti a fi ọwọ kọ ti on nka, to o si ju pẹlu.

Laisi ani ani Sir George Lewis ṣe iṣẹ iṣẹ ti o fi ndaraya laşeju bi ko ba si si ti ẹkọ iwe ti o kunri mọ ni, boya ẹmi rẹ iba gun si i, Igbati o wa lẹnu iṣẹ ati igbati ko si, ni ika iwe ni ikọwe, ni isi kọ iwe. O fi iṣẹ oniwe irohin 'Edinburgh Review silẹ lọ ṣe iṣẹ Chancellor of the Exchequer; nigbati o si şiwọ ninu eyi o mu iṣẹ a nṣe ẹda awọn iwe Greek ti a fi ọwọ kọ awọn eyiti o wa ni *British Museum*, ṣe. O gbadun a nkọ ẹkọ awọn iwe atijo ti o di piti. Ọkan ninu awọn ẹkọ, ti o kundun, eyiti ki iṣe gbogbo enia lo saba, ni ti wiwadi otitọ ti o wa ninu ti awọn kan ti a sọ pe wọn pẹ pupọ laiye, eyiti gẹgẹ bi aşa rẹ, o nṣe iyemeji si tabi ti ko gbagbọ. Ẹnu iṣẹ yi ni o wa gbagba-gba nigbati o nṣe ayan a nwa awọn ti yio dibo fun ni Herefordshire ni ọdun 1852. Ni ọjọ kan ti o ba ẹnikan sọ pe ki o dibo fun on, cluwarẹ kọ jalẹ. O wa dahun o ni "o dun mi pe o kọ lati dibo fun mi, şugbọn boya o le sọ fun mi bi o mọ ẹnikan ni agbegbe yi ti o pẹ pupọ laiye ki o to ku!"

A si tun ri ọpọlọpọ ninu awọn ẹgbẹ Sir George Lewis ti nwọn a mu ti iṣẹ iwe ṣe nitori nwọn ba ti ṣe iṣẹ Oşelu titi ti arẹ si de si wọn. Bi ilẹkun iṣẹ ilu ba tilẹ se mọ wọn loju, ti iṣẹ iwe ki iti nigbakan, awọn ti ki isi ri ara wọn loju nidi ọrọ ilu, bi o ba di ti awọn iwe arofọ-orin Homer ati ti Horace nwọn a di ọrẹ. Nigbati Ologbe Earl of Derby kuro ninu ipo iṣẹ Oşelu ni o ṣe iwe rẹ nipa 'Iliad,' iwe ti a o ma ka titi, nigbati awọn ọrọ rẹ ti o sọ ni Igbimọ ilu ba ti kuro ni iranti.

Bẹna ni nigbati ọwọ Mr. Gladstone ba dilẹ ni o nkọ iwe rẹ. "Student on Home," nigbana ni o si se itumọ iwe 'Farinis Roman State'; Mr. Disraeli si ṣe iwe 'Lothair' gẹrẹ ti o fi iṣẹ ilu silẹ. Ninu awọn Oşelu ti o ṣe iwe arofọ-itan, laika Mr. Disraeli, ni a ri Lord Russell ẹniti o ṣe kutupu ninu kikọ iwe itan ilu ati iwe itan igbesi aiye awọn ẹlomiran; Magnus of Normanly ati Lord Lytton alarofọ-itan ti ko lẹgbẹ, ẹniti a ferẹ le sọ pe o nfi iṣẹ ilu daraya ni; iṣẹ rọ pataki ni ti iwe şişe.

Ni akotan iṣẹ niwọn-tun-wọnsi dara fun ẹmi ati fun ara. Bi enia yio ba gbadun ara rẹ o ni lati lo gbogbo ẹbun ara rẹ ti a fi fun. Iṣẹ kọ ni iṣẹ ọşẹ, afi aşegan; ki isi ṣe iṣẹ lile ni ko dara fun ara bi iṣẹ ti ko si iwuri, iṣẹ ti ko ni adun, iṣẹ ti ko ni ara kan ninu. Gbogbo iṣẹ ti o ba ni ere ninu dara fun ara; ki enia si wa lẹnu iṣẹ, ti o dara ti o si ni ere ninu jẹ ọna aşiri nla kan ti enia fi nri idunu.

Iṣẹ iwe tabi iṣẹ ero ori, niwọn-tun-wọnsi ko ṣe enia lọşẹ bakana bi ti iṣẹ miran. Bi a ba fi ẹwọn si i, o dara fun ara bakana bi ti iṣẹ ti a nlo ara si; o si dabi ẹnipe o şoro ki a to fun enia ni iṣẹ ti o pọju lọ ṣe, bi a ba nro ti ara lile Ki a jẹ, ki a mu, ki a si fi gbogbo aiye ẹni sun, nṣe ọşẹ ju. Aişekan ma ntete gbo ni ju iṣẹ şişe lọ.

Şugbọn ko si ọgbọn kan ninu aşegan iṣẹ. Ni gasikia, adanu nla ni, papa ti a ba fi paka-nleke tabi ipaya kun. Ipaya tilẹ yara pa enia ju iṣẹ şişe lọ. A mu ẹru ba ni, a jẹ ni lara bi igbati iyanrin ati okuta ti ilọ ara wọn kikankikan ma ngbọ ẹsẹ kẹkẹ. A ni lati gafara fun iṣẹ aşegan ati ipaiya

Nitori aşegan iṣẹ ero ori jẹ atekunşe; bi o ba si, ti pọ to, bẹ ni iko arẹ ba ni to,

ti isi pa ni. Aṣegan iṣẹ, ero ori, si lẹ yi enia lori, gẹgẹ bi enia to nlọ ẹgun ti le ṣe aṣeju, ti a si da lẹhin nibiti o ni on ndan eyiti ipa rẹ ko to wo.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---

## OKO AJE.

Ọkunrin kan wa ni sa kan ti orukọ rẹ njẹ Lugbolugbo, ara Ominipetu li Oje Ile ni iṣe; janduku enia si ni; iwa rẹ ni awọn ara ilu rẹ lara jọjọ, nitori ti ko ka enia tabi ohunkohun si, bẹni nwọn ko ribi ti i si; ọkunrin yi lo si ṣe jijadi awo ti nbẹ ninu Aje Irawọ. Ẹjọ kan de si arin aburo rẹ kan ati ẹnikan, ọran na si di eyiti awọn agba wipe yio de Irawọ. O farahan gbangba pe aburo Lugbolugbo lo jẹbi, ṣugbọn o fi ọwọ sọ aiya fun aburo rẹ pe ki o sa keri Irawo. Nigbati nwọn nlọ, Lugbolugbo tẹle wọn. Ofin nlaula ni nigbani pe ẹnikẹni ko gbọdọ mu nkan ija kọju si Irawọ. Lugbolugbo rọ ada kekere kan, o si so o mọ ara rẹ nisalẹ ṣokoto. Gbogbo awọn to ri i ṣebi arun ara rẹ ni. Pẹlupẹlu, li ọjọ ti nwọn de ibode Irawo, Lugbolugbo nṣe bi ẹniti njẹrora arun yi lọpọlọpọ, tobẹ ti awọn onibode ko ka a si ẹniti nwọn iba tuwo. Bayi ni Lugbolugbo ṣe titi o fi mu ada re wọ ilu Irawọ. Nwọn tun da aburo rẹ lẹbi li afin Onirawọ, ṣugbon ko gba idajọ wọn. Nikẹhin nigbati a mu wọn de igbo Polo, bi awon ẹlẹjọ mejeji ti dobalẹ, ti Polo si nfi ẹfun afi osun kun ọkan, Lugbolugbo sa ti mọ pe aburo on ni Polo yio pa, o si sare lọ sinu agbo lojiji, o si fi ada rẹ ge ori Polo ati ẹniti o nfi ẹfun kun lori lojukanna, o si ko gbogbo ọpa Oriṣa-oko to wa ninu igbo na le ejika rẹ, o sa sinu igbo, o si ba ọna miran lọ si ilu rẹ. Ihin agbara rẹ ninu ogun sisa ti awọn ara Irawọ ti ngbọ ko jẹ ki ẹnikẹni ninu wọn daba lati lepa rẹ. Lati igbana ni nwọn ti ima fi ṣe ọrọ sọ wipe—

"A ki i mu ele re Irawọ;  
Ṣugbọn Lugbolugbo wipe  
On a mu t'on f'oju kan Polo."

Lati igbana pẹlu ni Aje Irawọ, ti a kọ mọ ni olori gbogbo aje, bẹrẹ si ṣubn titi di ọni, tobẹ ti ko fi si ẹni to tun jẹ mu ekeji rẹ lọ ṣibẹ li aiye isisiyi. Ohun ti Lugbolugbo ṣe yi si mu irifin ba gbogbo aje fun sa diẹ ni gbogbo ilu ti ihin na de. *Ṣugbọn "bi a nṣu u li akara, bi a nṣu u li ekuru,"* awọu alawo ko sa ni jẹ ki awo wọn bajẹ, niwọn bi o ti ṣe pe ninu rẹ ni ijẹ ati imu wa fun wọn. Nitorina ni nwọn wa iro kan pa lati fi bo gbogbo rẹ; lẹhin ọbun diẹ, iri si sẹ bo gbogbo itiju na. Nisisiyi, loju ọpọ enia ti ko mọ ijoko nkan wọnyi, awọn oko-aje wẹwẹwẹ to wa larin wa jasi ohun ribiribi; awọn alaigbọn ko si nle tete ja ẹtan awọn alawo, bikoṣe lẹhin igbati nwọn ba ti ṣofo pipọ nipa titẹle wọn; ọpọ irunu ati ibanujẹ ni isi kẹhin lilọ si oko-aje. Irunu a de, nigbati o ba ri i pe a ko ri ọrọ tabi ohun kan pataki dimu nipa ti ọran ti o ba lọ; ibanujẹ a si de, nigbati o ba si ri i pe kaka ki ọran ti o ba lọ yanju, ṣiṣe ni aje tubọ ba a da kun u.

Ninu ọrọ wọnyi, a ... ṣe akiyesi ohun mẹta. Ekini ni pe, awọn agba igbani mọ iru ohun buburu to wa ninu mimu ara-eni lọ si oko-aje, nitorina, nwọn ṣe gbogbo ọna lilọ si oko-aje ni hiha, nwọn si to ofin lile yi i ka lati fi da enia lẹkun lati ma lọ. Pẹlupẹlu, a ka a si ohun itiju fun ọba ati awọn igbimọ ilu nigbati nwọn ko le tẹ awọn enia wọn; nitorina ni nwọn ṣe nsa gbogbo ipa wọn lati pana iru ọran bẹ. Iku ọba, aisimi awọn ijoye, ati wahala awọn ibatan ki iṣe ohun ti awọn enia wa iba ma fi ọwọ dẹrẹ mu bẹ ni gba lailai. Ekeji ni pe, a ko gbọ pe Polo ṣi ẹnikan pa ri, eyi fihan pe awọn onidajọ wonni ki iṣe imẹlẹ lati wadi ẹjọ finifini ki nwọn to da are ati ẹbi. Ekẹta ni pe, bi awọn enia ti ngbọn si i, ti oju si tubọ nla si i, ko si ẹnikan to tun jẹ ṣe iyọnu lati mu ekeji rẹ lọ si Irawọ Ogbọn nwọ ogbọn, okunkun si nka kuro.—*L.*

APATA.

---

### MR. NICHOLAS JOHNSON.

Mr. Nicholas Johnson of Lagos who lately arrived from London after an absence of five years will address the congregation of the First Baptist Church at Broad Street to-morrow evening.

During his stay in London Mr. Johnson joined the Baptist Mission of that place and was publicly baptised.

---

## Prince Adeyemi of Ife.

Prince E. A. Adeyẹmi, President Judge, Ifẹ Native Court Administration, arrived Lagos yesterday to witness the Dedication Service of the African Bethel Church Cathedral.

Prince Adeyẹmi represents his father the Ọni of Ifẹ.

To master Gabriel Adeyẹni his brother, and to Brights' family we say ẹ ku a fojuba.

OLUṢAKIN.

*EKO AKETE*

EKO, SATURDAY, NOVEMBER 24, 1928.

## GBAJARE ỌRỌ ELEKO, O, ALADUGBO!!!

Ilu pa lọlọ nipasẹ ti ọrọ ẹjọ Prince Eṣugbayi Eleko a si gbọ pe ara ọpọlọpọ enia ni ko balẹ gẹgẹ bi gbogbo rẹ ti dakẹ win bayi loju wọn.

Ni ọsẹ diẹ to kọja ni a sọfun ni pe Eleko ti yan Lọya Moore agba lati ma ba ẹjọ on na lọ ni Kotu Ganran a si mọ pe Ọgbẹni na ko jẹ jafara lati ṣe gbigbe dide ọrọ na ni akoko ti o ba ya: Kosi ẹniti yio ka Idajọ are ijelo ti o de lati ilu Ọba ati Iwe Aṣẹ Ọba King ki oluwarẹ maṣe mi kanlẹ pe iṣisẹ siwaju ọrọ na ni Ilu Ọba ko ṣai ye olukuluku; lori didakẹ didi ti gbogbo rẹ si dakẹ bayi ko dumọ ọpọ Enia ninu ni ilu: gidipa a tilẹ gbọ pe awọn kan ranṣẹ wa si ilẹ yi lati idalẹ lati wa mọ igbati Eleko yio tun fi ẹsẹ mejeji wọ ilẹyi a si sọpe awọn enia sọfun wọn pe riro ẹjọ na koiti ya ni Kotu Ganran Eko.

Nitotọ o le ni oṣu marun lati igbati Ilu ti ri iro jijare Apili ẹjọ na ni kotu Ilu Oyinbo ka, loju ẹnikeni o dabi ẽnipe ki Idajọ na jẹ lilo Ijọba lati fi mu Eleko bọ w'ale: ṣugbọn bẹkọ, ọkọkan ni a nyọ ẹsẹ l' ẹgan: ohun ti o mu ẹjọ na lọ silu Ọba ni pe Eleko fẹ k' a fun on laiye lati ro ẹjọ ti ẹnu on pe kini on ṣe ki on to di ero Ọyọ ọsangangan lati ọdun kẹta ti Ijọba ti wa on lọ awọn Adajọ Kotu Abẹsẹ Ọba King ni Ilu Oyinbo si ri si pe ki nwọn da ẹjọ na pada wa sibi ki nwọn tubọ wa idi rẹ niwaju Adajọ Ọlọla M. L. Tew Igbakeji Adajọ Agba a si sọpe a ti fi Iwe Idajọ ti Kotu Ilu Oyinbo na si Kotu Eko o wa ku ki a fi ọjọ kan si riro ẹjọ na.

Ṣugbọn ohun ti o ru pupọ enia loju nipe ki lo tun ku ti o da riro ẹjọ na duro. Loju wa ẹjọ yi ki yio jẹ siṣe alairo nitori nigbati o ti wa ni Kotu nibi kosi hila-hilo kan mọ.

Ohun ti a le sọ nipe ki awọn ti a ti yan lati ṣabojuto ẹjọ yi ṣe kokari ati jigiri lati dide si riro ẹjọ na nitoripe ara ọpọlọpọ enia ni Ilu kobalẹ nwọn fẹ mọ bi ẹjọ na yio ti kusi ati bi yio ti ya si.

Niwọn igbati Aṣẹ Ọba King ti o sọpe ki a tun wa idi ẹjọ na nibi bati wa a le sọ fun ẹnyin Ilu pe ki ẹ maṣe foya nkankan nitoripe ko si ẹniti o to rọ Aṣẹ Ọba King danu iṣẹ suru ni o ku fun ẹjọ na ni riro.

Bi a ba tilẹ sọpe ara Eleko nta para ni Ọyọ fun ẹjọ na ni riro kia kia kosi ẹniti o le ri bawi niwọn igbati ko si ẹnikẹni ti o le wa ni irufẹ ipo ti Eleko wa loni lode Ọyọ, ti ko si larin awọn ẹbi rẹ tabi ni Ilu rẹ ti ara oluwarẹ le kunna titi a o fi sọfun oluwarẹ pe ki o pada ki o si ma lọ si ile rẹ ni alafia. Boya a le ri awọn enia ti o le ma sọpe kini gbogbo wahala wọnyi nipasẹ ẹjọ Eleko yi, ṣe alafia ni o wa ni Ọyọ idahun wa nipe eyi le jẹ bẽ, ṣugbọn tani a le mu lọ ni iṣaṣadidi kuro ni ile baba rẹ lalai mọ ohun tabi ẹṣẹ ti on ṣẹ ti oluwarẹ ko ni ṣe fitafita diẹ titi awọn ti o mu lọ yio tun mu bọ.

Wiwalọ ti Ijọba wa Eleko lọ jẹ ohun tabi wiwalọ ekinni ti a wa Ọba Eko lọ lẹhin igbati Eko ti wa labẹ Asia Gẹsi, ti a ba si dakẹ si ti Eleko bayi ki yio jẹ ohun ti o dara nitori ẹhin ọla: ti Eleko ni ari loni, talo mọ ẹniti o le kan lọla?

A tun kesi awọn ti ẹjọ yi wa ni itọju wọn ki nwọn jẹ ki Ilu gburo wọn ni ẹnu ọjọ mẹta oni nipa didide si ọrọ na!

Afara ni'ja Ẹkun.

## IRANTI ALAJI FAHM OLÕGBE

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe-Irohin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ f'oji,

Ọdun marun ki iṣe ọmọde ọjọ, ṣugbọn ni samani yi ọdun marun dabi ọdun mẹta, eyi fi nhan wa pe atumbọtan aiye ṣẹ nde.

dangerous driving in Lakeland, you have been doing things a little too fast during your honeymoon. If you had been on a honeymoon before you would have known better than to be in such a hurry. You should have gone about it quietly and gently. As it was, you became so excited that a policeman found you going at nearly fifty miles an hour, and, with a Stationary Car in front, you just managed to save your 'Pon my word, you could scarcely have been rashed.

JOHN BLUNT.

### WEST AFRICANS IN LONDON EXAMINATIONS.

Mr. I. Asafu Adjaye (Gold Coast) passed in the junior clinical surgical examiuation held last month, being placed third in the First Class Division in a list issued on October 11 by University College Hospital. Mr. Ansah Obuadabang Larbi, inter B.A. (London), of the Gold Coast, passed in the external intermediate examination in laws, L.L.B., held at the University of London, South Kensington, on September 24, 25 and 26. The result was announced on October 12. Mr. R. O. Staveley (junr.), of Lagos, has passed in the matriculation (full) examination of the University of London held in September. Mr. Staveley is a second year engineering student at the day technical college, Battersea Polytechnic. By passing this examination in the necessary subject for exemption, he has qualified for an exemption from the A.M.I.C.E. preliminary. He is to take the inter science examination shortly.

### PRIVY COUNCIL CASES FROM THE COAST.

Two West African appeals are to be heard in the Michaelmas sittings of the Privy Council, which opened last Monday. The first is that of Kwest Bediaku against Akosua Mianoo, an appeal from the Gold Coast Colony, relating to a claim to land and the regularity of certain proceedings. The solicitor are, for the appellant, Messrs. Ashurst, Morris, Crisp and Co.; and for the respondents, Messrs. Holmes, Son and Pott. The other appeal comes from Nigeria and is that of Zizer against the Judges of the Supreme Court of Nigeria, raising the question whether the appellant was rightly suspended from practising as a barrister or solicitor. Mr. E. F. Hunt is intructing for the appellant and Messrs. Burchells are solicitors for the respondents.

*West Africa* 20/10/28.

### TEXT BOOK COMMITTEE.

The Text-book Committee has held quarterly meeting throughout the year.

Although it cannot be claimed that as yet much has been actually achieved, a considerable amount of spadework has been done, and materials is being collected and prepared which should be of value in the future.

The Rev. F. W. Dodds, Superintendent of the Primitive Methodist Mission, and the Rev. G. Burton, Principal of St. Andrew's College, Oyo, have been making collections of Ibo and Yoruba folklore stories respectively. Many of these stories are very picturesque. In these Nigerian folklore stories it is almost invariably the tortoise who plays the part of 'Brer Rabbit' in the Uncle Remus stories and triumphs by his cunning. The present intention is to publish a selection of these stories in the principal vernaculars.

Publication in Yoruba does not present much difficulty, but publication in Ibo will. At the request of the Text-book Committee, a Sub-Committee was formed to enquire into the question of "Union Ibo," which has been formed from the different dialects and is an attempt to standardise the language. It is claimed that Union Ibo is now understood and used over a wide and increasing area in the Ibo Provinces. The Sub-Committee reported in favour of Union Ibo, but advised that the existing vocabulary, which had been originally formed for the purpose of translating the Bible, needed considerable amplification and Improvement. It is hoped that during 1928 it will be possible to second for this purpose an officer of the department, who will collaborate with members of the Missions and others who have an extensive knowledge of the language. It is doubtful whether much headway can be made with the publication of books in Ibo till this necessary work has been completed.

The manuscript of a book on the teaching of English has been sent to England for final revision and publication.

Collections of Ibo and Yoruba songs and airs are being made, and a member of the Committee, the Rev. E. G. Nightingale, has undertaken the preparation of a book on African children's games.

Arrangements have been made for the publication of a Yoruba Reader by Mrs. G. W. Sadler of the American Baptist Mission.

A Duala Grammar by Mr. E. A. L. Gaskin, Superintendent of Education, which it is hoped will be of considerable assistance to officers posted to the Cameroons Province, has been published.

A book entitled 'Plant and Animal Life in Tropical Africa' has been written by Mrs. Anislie in collaboration with her husband, Mr. J. R. Anislie, Senior Conservator of Forests. This book which has been illustrated, is now in the

press, and will shortly be published. In the opinion of members of the Text-book Committee to whom the manuscript was submitted, it is admirably suited for children in the higher standards.

The members of the Text-book Committee during the year were the Director of Education, the Deputy Director of Education, the Principal of King's College, Sister Agathon, Roman Catholic Mission, Rev. G. Burton Principal of St. Andrew's College, Oyo, Church Missionary Society, Mr. Herry Car, I.S.O., the Rev. F. W. Dodds, Primitive Methodist Mission, Mr. Evan B. Jones, United Free Church Mission, the Rev. E. G. Nightingale, Principal of Wesley College, Ibadan, the Rev. G. W. sadler, American Baptist Mission, and Mr. C. W. Wakeman, C. M. S. Bookshop, Lagos. During the absence on leave of the Rev. G. W. Sadler and the Rev. E. G. Nightingale, Miss Reagan, of the American Baptist Mission, and the Rev. J. A. Angus, Principal of the Wesleyan Boy's High School, served on the Committee.

A GENTLEMAN.

We have every sympathy with you on the last bereavement of your sister Mrs. Caroline Ellen Taiwo Adegun. But we this day rejoice with you for the recent promotion to the post of Assistant Chief Clerk. Here's the health of our friend: Emanuel Oluyele Bright.

*The Lagos Daily News, 20/11/28.*

THE RETIRING ARCHBISHOP OF CANTERBURY.

**Presentation at Lambeth Palace.**

London, Tuesday.

At a private ceremony at Lambeth Palace, Mr. Baldwin, the Prime Minister presented the retiring Archbishop of Canterbury with £14,000 collected from at least 15,000 subscribers in response to the invitation of a committee consisting of the Archbishop of York, the Prime Minister, the Earl of Selborne. Lord Dunedin, the Marchioness of Salisbury, the Dean of Westminister, Sir Thomas Inskip and the Rev. Scott Lidgett.

The total amount subscribed was £16,936, of which £2000 is devoted to a memorial at Lambeth Palace to commemorate Dr. Davidson's association with the place. Another presentation will be made by the Bishop of Western New York and President of Trinity, College Harford on behalf of the American Church. It will be in form of an address signed on behalf of the House of Bishops and the House of Clerical and Lay Deputies accompanied by a draft of 10,000 dollars in a gold casket—*Reuter.*

OLUṢAKIN.

---

The African Church Cathedral (Bethel) will be dedicated to-day at 4 o'clock p.m.

---

INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Orişi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

**Disinfectant Soap of Unrivalled Quality**

Use Magnet Carbolic Soap in your home—it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.

# MAGNET

## Carbolic Soap Tablets




WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## *Use Yaro for your baby!*

All experienced mothers give testimony in praise of "Yaro" as an indispensable 'Preservative' for 'Babies' Yaro has no equal in suppressing those complaints which make infants feel uneasy, especially during their critical teething period. Trust Yaro for all infants' complaints and use it for your baby. Price per bottle 3/3d & 2/3d.

## *Increased health for 3/- only.*

"Life Tonic Tablet" imparts tone and vigour to the body, renews every atom of the flesh, prevents brain fatigue and brings indescribable comfort to all mental workers.

Price 3/- per bottle.

## *A chance for female sufferers.*

Wireless Female Pills, the latest Scientific Discovery, have answered divers cases of functional complaints of disorders peculiar to women. These Pills serve as an effective fertiliser against barreness. Give "Wireless Female Pills" a trial and prove its reliability.

Our Anti-Plague Disinfectant Fluid kills dangerous flies, bugs cockroaches, etc., etc. 1/- and 1/6d per bottle.

### *Anti-Gon Pills.*

Get rid of veneareal diseases before they get rid of you by using Anti-Gon Pills—a reliable antisceptic against Gonorhea. 3/- per bottle.

WE ALSO STOCK:—

- Glaxo (large and small sizes)
- Vitafer—Brain Tonic
- Walk Easy Anti-Rheumatic Salt 3/6 & 2/-
- Pile Pills 1/6
- Vibrona Wine 7/6
- Lactogen
- Kalzana
- Effective Pile Remedy 7/6
- Back and Kidney Pills 2/-
- Zotal 1/6 & 2/6

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos,
*Branches*:—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
27, Moloney Bridge Street
109, Griffith Street, Ebute Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH ).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

ARẸMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S
## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size. 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*( A Native preparation for Women. )*

This medicine is an excellent remedy for Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILN ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

### Indents House.

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.
Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

## TO LET.

One Splendid Pleasure Car
No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

---

ia lowo lati se
ran, Iju, Eda,
aye wa arun mi sle.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko,

:o:

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orișirisi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorișirisi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun ḍidara wọn.

41, Offin Roa

*N.B :—Not obtainab*

GBOGBONIṢE FUN OWO WỌN.

Egbogi yi dara pupo fun
Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati o
ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BO
Postage 2/6 extra.


" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY
A AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.